# OKU JI DIDE, ỌLOPA ỌBA RI, O F'ES[illegible] FE E

**Ikede**

Ase ikede yi f u n gbogbo ẹnyin Okewa wa sis asojo wa wipe, ẹni kẹni ti owo ba syko si owo re ki o lete fi ranse ni- tori gbogbo ohun elo ti a fi nṣewo irohin lo ti gbe owo leri.

Ẹnikẹni ti ko ba fi tire ranse yo da iwe rẹ duro ao si se agbara lati gba owo re [illegible] owo re. Olori

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI-L'EJỌ

U. T. C

SERVES

YOU

WELL

VOL VII No 422 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA JULY 2 1955. (YE OW) ELETI OFE KOBO MEJI (2d)

## Irin Ajo Gomina Agba

Ọlola Gomina Agba ti Olu-Ilu Nigeria yio lo se abewo awon ilu yika gbogbo Nigeria.

Yio bere lati Ilu Ibadan lojo Tuesday' wakati meji pere ni yio lo ni Ibadan klo to k o j a si Ilorin l'owuro ojo keji.

Ni ojo keje osu July, yio de Kaduna, yio lo si Zaria, l'ojo keji lati Kaduna. Lati Zaria ni yio ti lo si Kano ni ojo kesan osu July, to ba si di ojo kewa osu July yio fo lo si Sokoto

Ni ojo kokanla osu July, ni Ọlola Gomina Agba yio fo lo si Maiduguri lati Sokoto, lati ibe lo si Jos lehin ojo meji.

Ni ojo Kerindinlogun osu July, ni yio kuro ni Enugu lo si Umuahia, Aba ati Port-Harcourt yio se ojo meji ki o to koja si Kalaba.



SIR JAMES ROBERTSON

Ni ojo kokandinlogun ni yio rekoja si Tiko nibe ni yio ti gba ona-ile de Buea.

## Oku Ji Dide, Olopa Oba Ri, O F'ese Fe e.

Irohin kan wa wipe, okunrin Ibo kan ti o nse ise reluwe nile Ibo, ti o si je okan ninu awon egbe Onibante salaisi ninu ile re ni Coal Camp, o si je okan ni ijo St. Bathalomew C.M.S. ilu yi.

Nwon gbe oku na lati ile re ni Coal Camp lo si Ogui lehin ti nwon se isin ikehin fun u tan ninu ile Isin, awon enia tele oku re lehin lati lo sin i ni Depot.

Bi nwon ti ngbe oku na lo ti nwon de Garage, beni keke oku na kose, posi oku ti o wa lori keke na si fi egbe lele, ohun ti o ya gbogbo enia lenu ni wipe, oku na ti nwon ngbe lo dide joko ninu posi

Agbako! kilotoyi, gbogbo awon enia ti o ngbe oku lo, ati awon ti o mbe ni Garage, olukuluku salo si arin oja. Bayi ni oja ba daru ti ariwo nse ge! Ile ise awon Olopa ti o mbe nitosi ko reti fi gboran.

Nwon ran Olopa kan jade lati lo wo ohun ti o sele. Bi o ti de Garage ti o ri oku na ti o nfe bosile lati inu posi, Olopa siyan, ko duro gba obe, o si fere daku ki o to de Office. Nigbati awon Olopa yoku ri bayi, nwon ko le duro bere ki ti o ti je, nwon bere si tilekun Oyinbo Elewon kan ti o ri gbogbo okun ti o sele yi li o mu oku na lo sodo re, o we fun, o si fun ni aso ti o wo lo sile, sugbon ko si eniti o le na oja lojo na.

## Oro Ijoba Pelu Alapansanpa Ko Dogba.

**Ibadan** Irohin kan wa lati ilu Ibadan wipe Egungun kan ti a npe ni Alapansanpa ati eyiti a npe ni Atipako pelu Ijoba Ibadan ko se dee dee.

Gegebi asa isedale, bi odun Egungun ba mbo bayi gbogbo eru Atori ti nwon ba ru wo ilu ni nwon o ta tan patapata. Gbogbo akoko ti nwon ba se odun Egungun ni awon ara Ibadan ni lati lo egba, atori si ara won lara ojo gbogbo ko to ojo ti nwon ni lati lo tetafo si ojude Olubadan Ati Egungun nla ati kekere ati eyi ti nwon ngbe pon sehin ni yio mu egba atori dani, nitoripe nwon ka a si eriwo aigbodo-mase, asa won ni.

Awon Egungun bi Atipako, Alapasanpa, Ololu ati Egungun Olopa je eyiti awon Dankare ati ogiripa enia ma ntele lehin pelu egba atori, eniti nwon ba lupa lojo ti nwon ba jade nigbani, je apagbe.

Sugbon aiye ijoun ko jo ti isisiyi. Li odun esi ore ti Egungun Alapansanpa da lojo na, koiti tan nile titi di oni, Nitorina, ki akoko odun Egungun to to, Awon olopa ti lo ba Alapansanpa, Atipako ati Ololu wipe odun odunni ko ni jo ti esi, enikeni ko gbodo lo atori

A gbo wipe, awon egungun na taku mo ijoba lowo wipe, bi o ba kan oran ti awon ko fi ni lo egba atori tabi pasan, awon ko ni jade. Beni ko si nse didun mu Olubadan wipe ki awon egungun wonyi mase jade.

Oro po nibe.



E wo aworan oke yi, Oloye I. B. Akinyele O.B.E., Alaiyeluwa Olubadan ti ilu Ibadan to nsi Ile-Itesiwaju, "Ile nla to mba ole leru" ti awon Oyinbo Onisowo U.A.C. ko si ilu Ibadan.

Kokoro Golu l'a fi le Alaiyeluwa Olubadan lowo ti o fi nsi ile na.

# Nigerian Railway
## AKIYESI
### ODUN ILEYA

Enikeni ti o ba fe fi Wagonu ko awon eran agbo wa fun Odun Ileya ki o tete kowe fun Wagonu gegebi a ti to si isale yi:—

(A) Lati Kano ati awon Ibudo re de Nguru.
E kowe si:— SENIOR ASSISTANT,
Traffic Superintendent, KANO.

(B) Lati Minna ati awon Ibudo to mbe l'agbegbe Minna Ko kan Kano:
E kowe si:— DISTRICT SUPERINTENDENT,
ZARIA.

(C) Lati gbogbo Ibudo Minna wa si isale.
E kowe si:— DISTRICT SUPERINTENDENT,
Ebute - Metta Junction.

Gegebi a ba ti ri iwe gba l'a o fi se eto won, be gege l'ao si fi ma fun won ni Wagonu. Oruko eniti o fe ko awon eran agbo nikan ni a o fi sile.

Railway Headquarters, Ebute - Metta. 24th June, 1955.

R. B. EMERSON,
General Manager



## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oririsi aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. JO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos



## Ojulowo Awure Ita'ja

Enikeni ti o ba nfe ki oja on ta kia-kia, Iwe Irohin Eleti-Ofe ni ojulowo awure ita'ja.

Wa polowo oja re sinu Eleti-Ofe



## Mo Gbadun Siga PIRATE





## A ki i Gbe'le Gb'ofa Lai R'ogun.

Okunrin kan ti oruko re nje Rufus Okelasu ni eniti o je alabagbe ile kanna po fi irin lu lori ti ori re si gb'ogbe.

Nigbati nwon mu Tunde Santos eniti o fi irin lu Okalasu lori de iwaju adajo ni kotu, fun esun wipe o lu Rufus, ko fa oro re gun, o ni on jebi, ati pe idaru okan l'o wa fun on, ti on ko fi mo igbati on se ise yi.

Agb'ejoro oba sofun adajo pe nigbehin-gbehin l'awon to mo wipe ori okunrin na ko dogba. Iya re si jeri si eyi.

Awon enia meji to je ibatan re l'o bo siwaju, adajo si pa lase wipe ki enikokan duro ponun medogbon-medogbon wipe odaran na ko fa ijogbon fun osu mejila.

Eniti o fi irin lu s i m b e nile iwosan (Hospital) nisisiyi.



OLOYE ANTHONY ENAHORO

Aworan oke iwe wa yi niti Oloye Anthony Enahoro, alaalabojuto eto ilu (Minister of Home Affairs) ti Ijoba Iwo-Orun, on ni eniti Oba Onogie ti Ilu Uromi fi je oye Adolo ti Uromi lojo Satide tokoja. Oba Onogie paapaa lo se etutu ifijoye na fun Oloye Enahoro.

## Abo Iwadi Owo Ise Awon Osise Ijoba

Abo ti Oluwadi ękun'wo isę awon osisę Ijoba (Ogbeni L.H. Gorsuch) ye ni ase alaye gbogbo abo iwadi re niba soki-soki ti ylo ye enyin onkawe yekeyeke si isalę yi:-

Oluwadi ni ki Ijoba fi owo bi sile Marun lori Ponun kokan owo ti awon osisę Ijoba ngba kun owo awon osisę ti ko de ipo óga, (Junior Service) ati owo bi sile meji bę gęgę kun ti awon osisę Ijoba to wa nipo Oga. (Senior Service)

Abo iwadi owo awon osisę Ijoba yi gbe fun awon osisę Ijoba ti awon ję onisę-owo (Technician) ju awon akowe lo. (Clerical Service), idi eyi ni wipe awon enia yara si isę akowe pupo ju isę-owo lo, idena pupo ni o si ma wa nigbati nwon ba nwa awon enia, to ni ękp-iwe to yekoro sibi isę-owo (technicians).

Oluwadi ni ki gbogbo iyipada owo awon Osisę bere lati ojo kini osu October, 1954.

## Ole Ajimoto Lo Se'won

Bode Ayodele to ti di eleye ile Tuba, to lo ji Moto Loya Lambo ati eru Ogbeni Rayne ara ilu Amerika ni, adajo Kotu Yaba ju s'ewon odun meji.

O ti koko tete l'epo oko o jaga ni kotu San-Tunde si ita Tinubo wipe on jebi, otito ni on ji eru ogbeni Rayne adajo si ti ju si ewon odun meta odun meji ni Kotu Yaba, odun meta ni Kotu Eko gbogbo re jel odun marun gbako pelu odun meji fa'be awon olopa, Iyen ni pe yio ma lo fi ara han lodo awon olopa oba fun odun meji lehin ti o ba lo asiko re tan logba ewon.

Ilu yio simi die lowo Ayodele ijogbon.

## Oko Oyinbo Kan Tan Sori Yanrin

Akassa Oko Oyinbo kan, ti a npe ni S/S Enugu ti o ma nko Eedu ati Ero wa si Eko lati ilu Port-Harcourt, ni a gbo wipe nigbati o nlo lati Eko si Port-Harcourt Okun le tobe, ti oko na ko mo igbati o fi sina ti o si lo gun ori yanrin ibe ti o gbe tan si, ti ko le lo si iwaju tabi ki o pada sehin.

Awon oyinbo Elder Dempster ran oko miran jade lo ba oko na, o si ko gbogbo awon ero inu re lo gunle si Ebute ilu Port-Harcourt Lehin na nwon ran awon oko Amona lo lati lo fa, oko na kuro lori yanrin, nse ni nwon se e ti nwon tun ran oko agbele lo sibe, aseti ni.

Oko wa larin agbami okun nibiti o gbe tan si. Ko si si ilu kan nitosi ibe- Awon onje ti nwon ko sinu oko fun jeje se ntan, ebi si npa awon osise inu re beni oke Ebute-meta ko se sure de.

Ijoba wa lo be awon oyinbo Elepo ti a npe ni Shell Co lati ba won fi oko ofurufu won ti a npe ni Helicopta ko onje lo fun awon osise inu oko na.

Bi o ti nko onje lo fun won beni o si nko won pada wa si Port-Harcourt diedie.

## Lemomu Egba Ahmadiyya Nlo Si Moka.

**Ebute - Metta** Lemomu Egba Ijo Ahmadiyya Chief Immam Shodeinde ti Ebute-metta yio lo si ile mimo Moka ati Modina pelu Iyawo re eleyinju-ege, Safuratu Shodeinde lojo Tuesday ose to mbo.

Lehin ti nwon ba se kokari esin tan ni Moka, nwon yio se ikede fun itoro owo kakiri fun kiko ile esin Musulumi (Mosque) si ile - Eko giga (University College) ti ilu Ibadan, ki nwon to pada bo wale ninu osu September, 1955.

Alo a dara, abo asunwon o.

## Iyanu Nla Leyi!

Okunrin aro kan wa nilu Kalaba, o ti ya aro to odun mejo to je wipe wiwo ni o ma nwo kiri ilu kole dide rin.

Ni ojo kan l'ose tokoja ni okiki kan wipe Udo Udo ti ise aro enia yi dide duro o si nfi ese re mejeji r n, eyi mu ki opo enia fe ri, nitoripe awon Hausa l'oma nso wipe "GANNI YA FI JI" eyiti itumo re je" Irohin koto afojuba" l'ede Yoruba.

Ni ojo ose tokoja ni awon enia pe biba ti nwo n nfi Udo Udo seranwo, nibe ni udo ti so itan ise iyanu na fun won. O wipe nigbati on sun l'oru ni on la ala ti on ri ajeji enia kan to yo si on pelu ewu awo-kanle, o si so fun on wipe "igbagbo re si Olorun to ki a san esan re fun o"

Lehin eyi, ni abami enia na pase wipe ki on dide duro on si dide duro; nigbati on ji l'owuro ojo na on mo pe ala ni on la, sugbon on yio gbiyanju wo boya o le jebe. On dide duro, ha, abi a sese, o ni sise bi meji-meta, nje irin bere na niyen.

Inu gbogbo enia dun si, nwon si bere si ta l'ore, koda awon enia nti ilu miran wa wo aro to dide yi, nwon si nfun ni ebun.

Awa maridi ni ise Olorun.


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 2/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 52 Scarborough Gardens, Westminster, London, S.W.1. England


# Ileri Ko To Amuse



QLQLA IGHODARO .

Qlola Ighodaro ti ise alabojuto ise ilera ti Ijoba Iwo-orun se alaye gedegbe wipe Ile Iwosan (Hospitals) to mbe ni awon ilu abe abo Ijoba Iwo-Orun je merindinlogun-awon ti a si tun nko lowo nisisiyi je meje.

Nigbati a ba pari awon ti a nko lowo wonyi ti a si si won fun lilo, ki yio si agbegbe kan ni Iwo-Orun ti Ile-Iwosan ko ni si.

A so si eto lati fi han enyin okawe wa wipe ileri ti awon egbe Afenifere se nigbati awon nse ikede wipe ki e dibo fun Ope, okan pataki ni nwon ti tun muse yi ninu opolopo eyiti nwon ti se amuse won ti a ko le ma ka a lesese fun yin. A so wipe pataki ni eyi nitoripe "lera l'ogun Oro"

Enyin na ti mo iyato to mbe l'arin egbe Afenifere (Action Group) ati awon egbe Agb'odegba miran

ILERI KO TO AMUSE


## THE NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

### ILEYA SHILLING FNUD (JULY, 1955)

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday 11th July, 1955.

Withdrawals can only be made by depositor in person and on production of his passbook. In case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such application to be accompanied by the depositors passbook, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 6th August, 1955 and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the Depositors' surnames on the date shown hereunder and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Monday, 18th July, 1955.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| A | to | B | Monday | 11th |
| C | „ | H | Tuesday | 12th |
| I | „ | N | Wednesday | 13th |
| O | „ | R | Thursday | 14th |
| S | „ | Z | Friday | 15th |
| A | & | O | Saturday | 16th |

For the year 1956 deposit will be taken as from Monday 8th August, 1955.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.



## Chairs For Rent

APPLY

OFE

NO. 3. AIBU STREET LAGOS

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

28 Kosoko Street, Lagos — "ETI-QFE LAGOS"

P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL. VII NO. 422 LAGOS SATURDAY JULY 2 1955.


## Ajodun Kejo Eleti-Qfe

"BI OLUWA BAWA PẸLU MI, TANI LE KOJU IJA SI MI"

A fi wosifa wa yi dupẹ ailopin lowo Qlọrun, Qba awa eda, fun ore ati anu re ti ko-lopin l'ori Iwe Irohin wa, ELETI-OFẸ, nleu gbogbo igbokegbodo, ofii on ola a, eyiti o je ti iṣe Iwe-Irohin ti a fi la odun kẹjo Iwe-Irohin wa yi ja, ti Qba Oga Ogo Olodumare ko je ki a ni ipalara, lodo Ijoba ati lọdọ awọn enia. A dupẹ fun Qlọrun nigba okẹ aimọye.

Gegebi ase awon Musulumi, ti Olorun Oba ni ohun isiwaju layekaye, li a se fi ope fun Oba Alali-arasi na gidigidi, awa nilati dupe lopolopo fun enyin alatilehin wa, mpa Ipolowe oja sinu Iwe Irohin wa (Advertisers) enyin Asoju Iwe Irohin wa nilu Eko, Nilu Oke, Nile Hausa (Oke-Oya) ati ni Oke-Okun (Gold Coast) to fi kan awon Asoju wa nilu Oyinbo (Europe) enyin Onibara wa, enyin ckawe wa ati enyin Oluta-Iwe Irohin wa, (Vendors) gbogbo nyin l'adupe fun u gidigidi. Ki alafia ati ibukun ailopin ti Olodumare masai ma ba gbogbo wa gbe lai ati titi lailai.

Gegebi ise wa atehinwa, a fe ki e mo amodaju wipe l'orekore ni ao ma fi irohin aladun to yin leti, ao si ma se alaye ise ilosiwaju ile wa, eyiti Ijoba Iwo-Orun nse lai sinmi si awon Olu-ilu wa, awon ileto ati abere'ko wa.

A dupe fun t'omode-t'agba l'okunrin,-lobinrin, gbogbo nyin l'ase ope fun keri o.

## Iyan Mu Lorile Aiye

Lati Qwo ESQ IKOYI

Iyan mu, mu, mu. o pa oba Olomo, o pa igba eranko, o pa agbagba mefa, Ojo pata, pata, pata, kan sile omo adie sare si i boya agbado ni. Omo lo da eepo isu sori atitan, Alamu sure si i, boya, yio ri nkan je, nigbati kori o kigbe ha! Nigbati omode gbo, o ndaku lo Abanimu-adie fi ojugun bo, aladie wipe ki o pele o, o dahun wipe, a ki dupe ara eni. A ki dupe ara eni bi ti ewo? Eni iku pa ko to nkan, ojo-jumo ni ebi npa ni. Gbogbo oro nwonyi je oro Ase.

Jowo enikeji, nipa oro ti a mba bo. Mo ni lojo kan, iyan mu ni ile Ife Qye-ilu-agbo tabi Qyelagbo iyan na po. Orunmila ji li owuro, o gbe Iporun re lule o nwipe:-

Ojumo mo,
A ko gbo poro, poro odo,
Qganjo gan dundun,
A ko gbo giri giri ese,
Afaimo, ki Awo ma sun
li ebi, afaimo

Orumo tun gbe Iporun sile, o gbe Ikin, o da a poki, poki, o da sile o tun bere si ki i bayi pe:-

Timo, timo li a ndifa Aditi
Kumbo, kumbo li a ndifa
Adeta, A da fun Orumila
A ni ki o jade kuro nilu
Qrunmila gbo oru.

Lojo ti a nwi yi, Iyan na mu, Ojo ko ro, Isu ko ta, Agbado ko gbo, araiye nkigbe ara orun nlogun. Gbogbo awon Irumole li a ti se lakun orun mo. Araiye ko le takun lo si orun, beni ara orun ko le ro wa ibi aiye.

Awon araiye be akala kio ba gbe Ahun lo fi se etutu lorun, Akala gbe Ahun si jojo ereke. Nigbati Akala de Qrun Ahun ko lati bo sile o si fi ona ofun Akala se ile titi di oni. Eyi lo mu ki Akala so gege.

Araiye tun fi ebo miran ran gunugun, Nigbayi ni ona la. Sango ke riri lajule orun, araiye fi igbe ayo ta, nwon bere si fi owo rara owo fun isami wipe ki ojo ro. Awon araiye bere si da oko, nwon ngbin isu, agbado, ewa ere e, ati awon ohun jije.

Nwon se eyiyi ko to iwon osu kan ni orisa oko be yo lati ajule wa si aiye lati wa ohun je, Isu ti awon Agbe gbin ti ko iti to osu merin, ni o bena sinu oko li ero wipe ki Isu oko na le jina, gbogbo oko isu jona raurau sugbo isu na ko jina, ni Orisa oko ba fi iwora ti ebi ti o npa a je isu ti ko jina. gbogbo ona ofun bere si yun, o wa bere si la epo, Epo ti o la fere to garawa kan.

## Okunrin Kan Ji Moto Gomina

IBADAN- Awon Qlopa nwa Qgbeni kan ti a gbo wipe o lo ji moto Gomina Western Region. lojo Satide to koja yi.

Gegebi awon olopa ti juwe re nwon ni o sese jade logba ewon ni, o je ara Ilorin, o si wo aso damask

Nigbehin, a gbo wipe nwon ti ri moto na ni orere Olubi Street ni Yaba ti awon Qlopa nso

Moto yi lo gbe Qlola Gomina yi ati aya re lo si Government House ki nwon to lo si ilu Oyinbo fun isinmi


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Eyin abiyamo ewa ra Omorela O dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ri orun sun daradara, o dara fun otutu iko ... ti o ma nba omode ja ni asiko ebin. Opolopo ... fun omo won ti won si so wipe o dara pupo ...

## Qmorela Baby Mixture

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

O wa lodo:

## Commercial Medicine Stores

QUALIFIED CHEMIST

10, Victoria Street Lagos



## Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials

PLEASE CONSULT:

## Okunowo Brothers

61, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

## Irora Lakuregbe

Iwosan re lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko sisẹ to, o nfẹ iranlọwọ Nitori iru amodi bayi lati ṣe ṣegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara.

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nṣe iwosan fun Lakuregbe, dan wo ki o lọ ra ọkan ni sọbu egbogi



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio dewi oluwa rẹ, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**

For Kidney and Bladder Troubles



## ENJOY YOUR OWN SONGS



SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERING OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS O

OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA



**NOW,**

**AVAILABLE**

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos,
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN






**ILE IBITI A NGBA AWON ERO NI ALEJO NI KANO**

Awon alejo ti oba wa si ile enia dudu ti oba sokale ni Kano lati inu oko ofurufu, ama gbadun ile yi, Simenti Burham ni afi ko, pupo ninu ile nlanla ti owa kakiri ile enia dudu, Sinmenti Burham ni afi ko won lati iwon adorin odun sehin, eyiyi je iranlowo pataki ninu idagbasoke ile enia dudu. Ko nse ni ile Nigeria nikan soso ni anse ohun yi, kakiri agbaiye ni Simenti BURHAM nse iranlowo fun ilosiwaju ati idagbasoke. O ti fi han gbangba wipe Simenti yi lo lagbara ju, on ni o si dara julo ni agbaiye.

# BURHAM

PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO. LONDON — BURHAM WORKS — PORTLAND CEMENT


## Always Read And Advertise In Eleti Ọfe

**Eleti-Qfe Kari Gbogbo Ile Nigeria, A Ti Nilu Okere, Wa Polowo Qja Re Sinu Eleti-Qfe.**






## Awon Obinrin Qyo Mbe'be Fun Ipada Sile Alafin

Awon obinrin ilu Oyó lo si Ibadan lodo Alakoso Ijoba Iwo-Oran, Oloia Obafemi Awolowo, nwón si bebé fun idapada sile Alafin Òyó, Oloye Awolowo fesi fun wọn wipe oro won dara o si dun ninu oo, sugbon ki nwọn pada lo silu won ki awọn lo se atunso oro Alafin pelu awọn Oloye ilu Qyo, bi eyi ba ti se, nigbana ni alafia le wa ti Alafin ba pada si Oyó.

Alafia ilu Òyó ati awọn enia inu re ni ijoba nfe; awon obinrin na si gba be, nwọn dupe pupo fun Alakoso Ijoba Iwọ-Orun, Oloye Awolọwó.

Enyin agbedegba, e pa'nu mọ oro Alafin ko ni hati-hati ninu.

## Ati Gbe'yawo Ko T'ejo, Owo Obe L'osoro.

OLOTU,

Jowó gba mi l'aye lati fi wonika mi yi bẹ Ijoba ilu Ejigbo ati ọba aji-se finni, Elejigbo, nipa orọ owo ori Iyawo ti a nsan l'ori Iyawo ọmọge (Wundia) nilu Ejigbo eyiti o fere to ogofa ponun (£120.)

Bi enia ba ni irufe owo yi lowo yio gbero ati kẹ ile, sugbon bi o ba ronu kan ti iyawo afẹsọna rẹ, ọ̀rọ̀ na yio yi pada, nitori ati le san'wo ori iyawo rẹ ki o to gbe.

Nitorina, a bẹ Ijoba ilu Ejigbo ki o ba wa fi eto si owo Igbeyawo, ki alafia ati ilọsiwaju le de ilu wa yi. Elomiran fẹ kọ ile omiran afe tun ile to ti jona kẹ, bẹni Elomiran nfẹ tun ile rẹ ṣe ki o se leso eyiti o le gbe ogo ilu yọ, sugbọn bi o ba ti gba Iyawo ti a ti jẹun di sipẹtẹlẹ, ni yio ranti okan rere wonyi?

Mo fẹ ki e fi ọro mi yi si aro e digidi, nitoripe opolopọ enia lo ti kọ ile ti ko le tunse, eyi ti ile re jona, ko le tun ko, gbese ti le opọ enia kuro nilu, elomiran ko tile ni ewu l'orun, irufẹ iwonyi ko ba te ki awọn alase ilu wa fi opin si owo girimọyan ti a fi afe Iyawo.

A ko le sai dupẹ lọwọ ọba wa Elejigbo, nitoripe o ti se wahala, o si na agbara pupọ lati fi opin si owo Iléyawo yi ninu ọdun 1952, nitorina, a bẹ Ijoba ibile ki awọn s'owọpọ pẹlu baba wa Elejigbo lati ba wa ṣipẹ fun awọn baba abiwẹrẹ ọmọge obinrin ti nwọn ki i se lẹẹ mọ, ayafi ki wọn ma ṣoti owo ife ọmọ wọn ti ọkọ yio san.

Emi ni omo yin,

Abiola Qlota (omo Ejigbo)

ABIDJAN.

# Ile Ite-Siwaju



Aworan oke yi niti Ile - Ita'ja ati ile - Ise awon oyinbo U. A. C. ti nwon ko si opopo Kotu titun ni Ilu Ibadan. Alaiyeluwa Oba Olubadan, Oloye I. B. Akinyele, O.B.E., l'o si Ile Nla na.

# ISLAND CLUB

## Election of Officers 1955/56.

The following officers have been elected for the year 1955/56.

Messrs. J K Randle (Chairman) Griffin (Vice Chairman) Ayo Reffle (Secretary) Bolaji Finnih (Treasurer) M. A. Thompson (Auditor.)

COMMITTEE MEMBERS :- Messrs. J S Adewale, Taju Thompson, Alex. Ola. Oni, M A Ogun, N N Hughes, Folorunsho Odulana, and A O Lawson.

WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

## AGRONOMIST

The Western Regional Production Development Board, Ibadan, Nigeria, invites applications for the position of Agronomist. The duties of the successful applicant will be to maintain liaison with all West African Research and soil survey organisations and to co-ordinate all cultural, fortilizer, and sundry experimental work required in connection with the Board's commercial plantations of Cocoa, Rubber, Oil Palms, Citrus and other tropical crops. Candidates must possess a good degree in Science or Agriculture, preferably honours, with some knowledge of Chemistry or Soil Science, and should have several years post graduate agronomic experience preferably in the tropics.

Salary will be in the range of £1,240 to £2,100 per annum (including; expatriation allowance where appropriate), point of entry depending upon candidates qualifications and experience; outfit allowances £60, free medical services; free passages for wife and up to two children or children's separation allowance at the rate of £75 per annum per child; free house with basic furniture; up to 10 o/o Provident Fund; home leave on full pay at the rate of five days per month of overseas service; tour initially 18/24 months with good prospects of renewal.

Applications, preferably in the candidates' own handwriting stating age, family, qualifications, practical experience in chronological order, present salary and address to the secretary, Western Regional Production Development Board, Ibadan, Nigeria, not later than 15th July 1955.

# Western Region Medical Services

VACANCY FOR SENIOR STORES EXAMINER

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Senior Stores Examiner in the Western Region Medical Service.

Scale of Salary:- D/A; £465-25-615.

QUALIFICATIONS:- Candidates must have had a good general education and practical experience in Store Work. A good knowlege of accounting is also desirable. Candidates must be of high moral integrity and possess good address. They must have had or be able to acquire within reasonable time a good knowledge of costing and Crown Agents indenting procedure and principles of storkeeping as practised in Government Department Stores. Actual experience in a medical Store as well as familiarity with the different kinds of Hospital Supplies enumerated in the Medical Store Catelogue will be an advantage. Candidates in the Government Service should have reached the grade of First Class Clerk or its equivalent.

DUTIES:- The Officer appointed will be required to check ledger records and store cards against actual stock balance in an allocated Medical Stores and, in the near future, unallocated Medical Stores. He will be responsible to the Senior Pharmacist in charge Western Region Medical Stores for compiling a report on each examination.

METHOD OF APPLICATION:- Application should be addressed to the Director of Medical Services Western Region Ibadan so as to reach him not later than the 31st July 1955.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the applicant's Department and be accompanied by a Confidential Report on the new Confidential Report Form.

# THE NATIONAL BANK

OF NIGERIA LIMITED

## ILEYA SHILLING FUND
(JULY, 1955)

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday 11th July, 1955.

Withdrawals can only be made by depositor in person and on production of his passbook. In case of distant depositors, early application for withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such application to be accompanied by the depositors passbook, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 6th August, 1955 and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the Depositors' surnames on the date shown hereunder and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Monday, 18th July, 1955.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| A | to | B | Monday | 11th |
| C | „ | H | Tuesday | 12th |
| I | „ | N | Wednesday | 13th |
| O | „ | R | Thursday | 14th |
| S | „ | Z | Friday | 15th |
| A | & | O | Saturday | 16th |

For the year 1956 deposit will be taken as from Monday 8th August, 1955.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.

## Awo Lo Ko Dagbere



Aworan apakan iwe yi niti Olola Ologbe Bode Thomas, oninurere olotito aromada. hun omokunrin ti o je irawo ilu Eko ti o salaisi nikan bi odun meji sehin.

ORUN RERE O.

## Awon Oba Iwo-Orun Nfe Da Si Oro Oba Alafin

A gbo wipe, lo'se to koja ni awon enia pataki-pataki pelu awon Alhaji bi ogun enia lati Abeokuta ati ilu Ibadan, ni awon lo s'odo Alaiyeluwa Oba Alake ati Alaiyeluwa Oba Oni ti Ile-Ife wipe ki nwon jowo ba won da si oro edekoyede to wa larin Alhaji Adeniran, Alafin Oyo pelu awon Ijoye re.

A gbo wipe awon Oba Alake ati Oni so wipe o dun ninu awon lati da si oro edekoyede na ki awon si pari re bi Oba Alafin yio ba gba imoran awon.

Sugbon ni ilu Oyo l'oni, Bashorun Oloye J.O. Ladokun l'agbo pe o so bayi:- Rudurudu ko le tan nilu Oyo niwon igbati Ijoba Iwo-Orun ti egbe Afenifere (Action Group je, alakoso re, ko ba gba ohun ti Oyomesi nfe, wipe ki a yo Alafin ki a si fi elomiran je oye Alafin r'opo re.

Oro Alafin koi ti ni iforiti.

## Ojo Alaruba Pa Bambari L'Eko

**Eko** Ojo kan ti o ro ni agogo meta oru Alaruba moju ojo keji so opolopo onile d asunta. Nse ni omi nwo iyara lo ba awon elomiran. Adugbo bi Anikantamo, Isale-Eko, Olowu, Elegbata, Okepopo, Kosoko, a fi bi enia gbe oko si ori omi, titi lo de odo awon Olopa (Police Station) ni Ita-Tinubu, osa ni gbogbo ibe. Nibe awon panapana nfi reba fa omi. Iru ojo bayi ki ise nkan ti o gbodo ya enyin okawe wa lenu rara, nitori eyiti yio ro fun odidi ojo mefa leralera mbo, ki olukuluku lo san sokoto re giri.

Die ni o ku ki a ma ri eja pa ninu omi yi.

## Sport's Today

### Alex Oni's Cup Final Today

#### YORUBAS XI TO MEET IBOS XI

All roads will lead to the King George V Stadium this afternoon where two regular finalists Ibos and Yorubas will play the Inter Tribal finals for the Cup donated by Alex Oni.

The Yorubas will be represented by Jaji, Sittu, Rashidi, Sulaiman, Williams, Yussuf, Shyllon, Salvador Ekunsunmi, Johnson, and Mutiu.

The Ibos will be Olisa or Ibiam, James, Ekwuoh, Offoh, Anyiam, Ntephe, Cyrill, Ijomah, Chuckwurah Anieke and Inronkwe.

The weather being well, fans will have full value for their money.

-- BASH OLUKOTUN

ARADAN DUSTING POWDER
FOR PERSONAL HYGIENE
FORMULA:- Boracic, Zinc & Amylum
THE EGBA TRADING ARADAN STORES
114, DENTON BRIDGE ST, P.O.BOX 2, EBUTE METTA.

REDIFFUSION
THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME
Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.
MAINTAINANCE FREE! ARE YOU A SUBSCRIBER?

WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

## NURSE

The Board invites applications from suitably qualified candidates for appointment as Nurse.

2. Candidates should be qualified locally trained Nurses and should possess varied hospital experience.

3. Salary will be in the scale £195 x 15 - £300, point of entry depending on experience and qualification.

4. Applications, accompanied by copies of Certificates and Testimonials, should be forwarded to reach:

THE PERSONNEL SECRETARY,
Western Regional Production Development Board, Secretariat,
Ibadan
not later than 7th July, 1955.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23373